“Awọn eniyan kan maa wa ni igbẹyin ijọ mi, ti wọn maa maa sọ fun yin nnkan ti ẹyin gangan tabi awọn baba yin ko gbọ, ẹ ṣọra fun wọn ”

Lati ọdọ Abu Huraira, lati ọdọ ojisẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- o sọ pe: “Awọn eniyan kan maa wa ni igbẹyin ijọ mi, ti wọn maa maa sọ fun yin nnkan ti ẹyin gangan tabi awọn baba yin ko gbọ, ẹ ṣọra fun wọn ”.

[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pe awọn eniyan kan maa han ni igbẹyin ìjọ rẹ ti wọn maa maa da adapa-irọ, ti wọn maa maa sọ nnkan ti ẹnikẹni ko sọ ṣíwájú wọn, ti wọn maa maa sọrọ pẹlu awọn hadiisi irọ ati agbelẹrọ, Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla maa ba a- pa wa láṣẹ lati jina si wọn ki a si ma jokoo pẹlu wọn, ki a si ma tẹti si awọn hadiisi wọn; ki hadiisi ti wọn hun yii ma baa duro ninu awọn ẹmí, ki a ma baa kagara kuro nibi lila kuro nibẹ.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/65076